## IṢEUN ỌLỌRUN SI ỌKÀN TI ONGBẸ N GBẸ

**Orin Dafidi 42:1-11; 63:1-11; 65:1-13.**

**ẸKỌ 447 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Alabukún-fun li awọn ẹniti ebi pa ati ti ongbẹ ngbẹ sipa ododo: nitori nwọn ó yo" (Matteu 5:6).**

Nigba ti a n dọdẹ ti a si n lepa Dafidi lati ọwọ́ Saulu ati awọn ọmọ-ogun rẹ̀, ọkàn Dafidi (ni isalẹ ookan-aya rẹ̀ lọhun) mí hẹlẹ o si n pongbẹ fun Ọlọrun. Ọkàn rẹ̀ bajẹ, omije si n ṣàn ni oju rẹ̀ tọ̀sán-tòru bi awọn ọta rẹ̀ ti n pẹgan ti wọ́n si n wi pe, "Ọlọrun rẹ dà?" Oun dabi agbọnrin ti agbo ikooko n lé titi ó fi rẹ̀ ẹ́ ti ọ̀fun rẹ̀ si gbẹ to bẹẹ ti o fẹrẹ má lè gbésẹ̀ kan si i mọ́. Bi kò bá ri ibi sá pamọ si, awọn ikooko yoo mu un nigbooṣe wọn yoo si pa á.

### Ibi Isadi Onigbagbọ́

Onigbagbọ́ paapaa ni ọta. Bibeli wi pe, "Eṣu, ọtá nyin, bi kiniun ti nke ramuramu, o nrin kãkiri, o nwá ẹniti yio pajẹ kiri" (1 Peteru 5:8). Eṣu n fẹ pa Onigbagbọ́ jẹ, tabi ki o fi agbára mu un kuro ninu sisin Jesu, ki ó si sọ ọ́ di ẹru eṣu.

Ṣugbọn Onigbagbọ́ ni ibi isasi lọdọ Jesu. A kà ninu Bibeli pe: "Orukọ OLUWA, ile-iṣọ agbara ni: Olododo sá wọ inu rẹ̀, o si là" (Owe 18:10). Awa n ké pe Jesu Oun a si yọ awọn ti Rẹ̀.

Adura Dafidi ni, "Nigbawo li emi o wá, ti emi o yọju niwaju Ọlọrun?" Ó n fi oju sọna de igba ti oun yoo lè wá si ile Ọlọrun ni Jerusalẹmu ki oun kunlẹ nibẹ niwaju Ọlọrun. Oun naa paapaa n wá ibi isadi. Ara ha yá ọ lati lọ ile-isin? Iwọ ha n reti akoko isin ti iwọ yoo ni anfaani lati kọrin, lati gbadura ati lati bá Ọlọrun pade nibẹ? Ibẹ naa ni iwọ ti le ri iranwọ nigba ti idanwo ati wahala bá dé.

### Ero Dafidi

Bi Dafidi ti n ronu ọ̀pọlọpọ igba ti oun ti lọ sinu Agọ gẹgẹ bi Ọlọrun ti sọ fun awọn Ju lati maa ṣe, (Deuteronomi 12:5-14), o rò ninu ara rẹ̀: "Ki ni ṣe ti inu mi fi bajẹ to bẹẹ? Ki ni ṣe ti aibalẹ ọkàn ati aisimi fi bá mi? Ó yẹ ki n dakẹ ki n si ni ireti ninu Ọlọrun, nitori Ọlọrun yoo ṣi ọna fun mi lati tun pada si ile Rẹ̀ ni Jerusalẹmu, emi si mọ̀ pe oju rere Rẹ̀ n wò mí bi emi ti n gbadura".

Dafidi rò pé wahala ti ó dé bá oun dabi igbi ati riru omi òkun ti ó n fẹ́ bo oun mọ́lẹ̀ ṣugbọn ó tu ara rẹ̀ ninu, niwọn bi o ti mọ̀ pé ni gbogbo igba ọ̀sán iṣeun aanu Oluwa wà pẹlu oun, ati pe ni alẹ́ orin Oluwa wà fun oun. Bẹẹ na ni o ri fun olukuluku Onigbagbọ́.

### Sún mọ́ Ọlọrun

Ki iwọ ki o to lọ si ile-iwe ni owurọ, iwọ ha n wá àye lati ka ẹsẹ Iwe Mimọ́ lati inu Bibeli ati lati kunlẹ beere pe ki Oluwa pa ọ́ mọ́ ninu iwa-mimọ́ ni gbogbo ọjọ́? Bi bẹẹ ni, Jesu wà nitosi rẹ jalẹ ọjọ́ lati fi ifẹ ati ìyọ́nú ràn ọ́ lọwọ. Nigba ti ilẹ bá ṣú, o dara lati tún ka Ọrọ Rẹ̀; ati lati dupẹ lọwọ Rẹ̀ fun awọn ibukun ti o ri gbà. Ni igba oru, Oun o fi orin Ihinrere si ọ lọkàn lati ṣi ọ lori ati lati kọ́ ọ. Ṣugbọn ki o ri daju pe iwọ fi eti silẹ nitori ọpọlọpọ igba ni Jesu maa n fi ọrọ orin ba ni sọrọ.

Ki ni ṣe ti a fi n wá si Sioni, tabi si ile-isin? Ki ha ṣe lati yin Ọlọrun ati lati san ẹ̀jẹ́ wa, awọn ohun ti a ṣeleri fun Ọlọrun lati ṣe nigba ti Ó gbà wá là? "Emi yoo fi ayé mi fun Ọ", ni a wí; nigbakuugba ti a bá wá si ile-isin lati yìn ati lati gbadura, a ni lati yẹ ọkàn wa wò. A ha wà fun Ọlọrun patapata sibẹ, tabi iwaasu lati inu Bibeli fi imọ-ti ara-ẹni ti ó wà ninu igbesi-ayé wa eyi ti o si yẹ ki a mú wá si títọ́ hàn wá?

"Iwọ ti ngbọ́ adura, …." Awọn wo ni o le wá sọdọ Ọlọrun titobi ti n gbọ́ adura? O ha jẹ pe awọn aṣayan eniyan kan ni o le tọ Ọlọrun wá ninu adura? Bẹẹ kọ́. Onipsalmu wi pe, "Si ọdọ rẹ ni gbogbo enia mbọ̀." Eyi fi hàn pe gbogbo eniyan ni o lẹtọ lati tọ Ọlọrun lọ. Olukuluku eniyan ti ó wà

layé nisisiyii, tabi ti o ti wà ni ayé rí, ti gbadura rí, tabi yoo wá kunlẹ lati gbadura si Ọlọrun nigbooṣe (Romu 14:11). Nisisiyii olukuluku ẹlẹṣẹ le tọ Jesu wá ki o si bẹ̀bẹ̀ fun idariji, olukuluku Onigbagbọ́ ni o si n wá sọdọ Jesu lati yin In ati lati dupẹ lọwọ Rẹ̀ ati lati beere iranwọ lati le wu Ọlọrun ni ọna gbogbo. Gbogbo awọn ti o kọ̀ tabi ti o ṣe alainaani lati gbadura nisisiyii yoo wólẹ̀ ni ọjọ́ kan niwaju Ọlọrun, wọ́n o si juba Rẹ̀.

Awọn ẹlẹṣẹ le gbiyanju lati sọrọ odi si wa, wọ́n si le gbiyanju lati kó wahala bá wa, ṣugbọn bi Jesu bá ti wẹ awọn ẹ̀ṣẹ wa nù, bi ọkàn wa kò si dá wa lẹbi, a ti sá lọ sibi isadi wa lọdọ lọdọ Jesu a o si wà ni ailewu nibẹ. A lè sinmi le E lati ṣe ohun gbogbo fun ire wa.

### Ẹni ti a Yàn

"Alabukún-fun li ẹniti iwọ yàn, …." Ọlọrun ha ti yàn ọ bí? Ẹnikẹni ni a lè gbalà, bi a bá si ti gbà ọ là, a ti yàn ọ́ lati jẹ́ ọmọlẹyin Jesu, nitori Jesu sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe, "Emi li o yàn nyin" (Johannu 15:16). "Alabukún-fun li ẹniti iwọ yàn, ti iwọ si mu lati ma sunmọ ọdọ rẹ, …." Onigbagbọ́ a maa sun mọ́ tabi wá si itosi Ọlọrun nipa adura, nipa sisọ ẹri ẹni, nipa titẹti silẹ si iwaasu Ọrọ Ọlọrun ni ile-isin. "Ki o le ma gbe inu agbala rẹ wọnni" -- agbala Agọ, ile Ọlọrun. Wo iru anfaani ribiribi lati jẹ́ ẹni ti a yàn lati ni ipin ninu iṣẹ-isin ninu ijọ! Wo bi a ti ni itara lati ṣe oloootọ ninu ojuṣe wa, yala lati bá olukọ Ile-Ẹkọ Ọjọ Isinmi wa ṣeto awọn iwe rẹ̀, tabi lati lo ohun-elo orin, lati jẹri tabi lati gbadura nibi pẹpẹ!

### Titobi Ọlọrun

"Nipa ohun iyanu" (ni ọ̀na iyanu ati ti agbára) ni Ọlọrun yoo fi dá wa lohun -- Ọlọrun ti ki i ṣe Ọlọrun igbala wa nikan, ṣugbọn ti i ṣe igbẹkẹle ati iranwọ gbogbo awọn ti o n gbé ni gbogbo opin ayé ati ti awọn ti o wà ni ọ̀na jijin réré ni oju òkun.

"Nipa agbara rẹ̀." Onipsalmu n gbiyanju lati sọ fun wa bi Ọlọrun ti tobi tó. Nipa agbára Rẹ̀ ni Ó dá ayé yii ati ohun gbogbo ti o wà ninu rẹ̀. Ó sọrọ, o si rí bẹ́ ẹ̀. Ó paṣẹ, awọn oke nla si duro ṣinṣin. Ó fi agbara di wọ́n ni amure ki wọn ba le maa wà ni gbogbo ọjọ, titi Ọlọrun yoo ká ayé bi aṣọ (Heberu 1:12), ti yoo si dá Ọrun titun ati ayé titun (2 Peteru 3:13). Ọlọrun n mú ki ariwo ati igbi okun parọ́rọ́, gẹgẹ bi Jesu ti ṣe fun igbi okun Galili; ni ọjọ́ kan Oun yoo si mú ki irọkẹkẹ, idarudapọ ati ariwo awọn eniyan buburu ayé yii ki o parọ́rọ́. Awọn ami tabi ifarahan agbara nla Ọlọrun -- ìgbì, ààrá, mànàmáná, irawọ ti n tàn, iṣuju òòrùn ati oṣupa, ìjì lile, isẹlẹ -- gbogbo wọn jẹ́ ifihan titobi Ọlọrun ti o ni ẹrù si awọn eniyan nibi gbogbo. Oorun ti ó n jí wa ni owurọ n fun wa layọ bi a ti n lọ ṣe iṣẹ oojọ wa ojoojumọ́, awọn awọ̀ oṣumare ti o n ta si oju ọrun ni aṣaalẹ a si maa mú ọkàn wa yọ̀ nigba ti a bá n ronu nipa ẹwà iṣẹ́ ọwọ́ Ọlọrun.

### Idupẹ

"Iwọ bẹ aiye wò". Iwọ fi ọkàn ṣiro rẹ̀ pé Ọlọrun n sọkalẹ lati wo apá ilẹ ti o n fẹ́ òjò lati pese rẹ̀ silẹ fun kíkọ ebè ati gbigbin ọkà! Oun ṣi ọ̀run silẹ Ó si bomi rin ilẹ oko naa. Nigba ti a bá kọ ọ́ ni ebè, omi ojo a mú un dẹ̀ lati le gba eso si ibi ti ooru ati omi yoo gbé mú un hù, Ọlọrun a si maa ṣọ́ awọn ohun-ọgbin ẹlẹgẹ́ naa bi wọn ti n dagba.

"Iwọ fi ore rẹ de ọdun li ade". A fi Ọlọrun hàn bi Ẹni ti O n fẹ́ dé ayé ni adé. Ni atetekọ́ṣe Ó dá oorun, oṣupa, awọn irawọ, "fun àmi, ati fun akoko, ati fun ọjọ́, ati fun ọdún". Bi wọ́n si ti n yi ni ipa ọ̀na wọn, ti wọ́n n fi imọlẹ ati ooru fun ni lẹsẹẹsẹ ni igba ọ̀sáǹ ati oru ni gbogbo agbayé, Ọlọrun a si mú ki ọkà ati ewebẹ dagba ki wọ́n si yọ eso ti ó sanra ninu ọgbọ́n ati itọju Rẹ̀ ti o rọnu. Ni ọpọlọpọ aginju, nibi ti a ko kọ ebè ti a kò sí fọnrugbin sí, Ọlọrun tilẹ pese papa oko tutu fun awọn maluu.

Awọn oke kún fún eweko-igbẹ, agutan pẹlu maluu si n jẹ lori papa. Awọn afonifoji kún fún ọkà, alikama ati barle. Gbogbo wọn n kọrin wọn si n hó fun ayọ̀! Iṣọkan wà ninu iyin si Ọlọrun, ti O fi ifẹ pese fun aini ti ẹmi ati ti ara fun gbogbo ọmọkunrin ati ọmọbinrin ati ọkunrin ati obinrin ni gbogbo ayé.

## AWỌN IBEERE

1. Bawo ni Dafidi ṣe ṣapejuwe ọ̀hàhà ongbẹ rẹ̀ lati wà ni ibi mimọ́, ani ile Ọlọrun?
2. Bawo ni o ṣe tu ara rẹ̀ ninu nigba ti awọn ọ̀tá n dọdẹ ti wọ́n si n lepa rẹ̀, ti oun kò si le fi ara hàn ninu Agọ ni Jerusalẹmu?
3. Ki ni Ọlọrun ṣe lati ran Dafidi lọwọ nigba ọ̀sán? ati nigba oru?
4. Ki ni Dafidi ṣe nigba ti ó wà lori ibusun rẹ̀ ni oru?
5. Ki ni gbọdọ jẹ́ ipinnu wa nigba ti a bá lọ si ile-isin?
6. Ta ni yoo wá siwaju Ọlọrun ninu adura?
7. Ta ni i ṣe alabukún-fun?
8. Ki ni awọn ohun diẹ ti Ọlọrun maa n ṣe lati fi titobi Rẹ̀ hàn fun awọn eniyan nibi gbogbo?
9. Ki ni Ọlọrun fi n bẹ ayé wò ki o lè mú ounjẹ wá fun eniyan ati ẹranko?
10. Nipa ki ni Onipsalmu n sọ nigba ti ó wi pé, "Nwọn nhó fun ayọ̀, nwọn nkọrin pẹlu"?